# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE. TẸNI GBOGBO LA WA

No. 577 SATURDAY APRIL, 11 1964 (2D)

## Akintọla Ṣi Ile-Ẹkọ Giga Ilesha Pada

ILESHA:— Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi ni Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun paṣẹ pe ki nwọn lọ ṣi Ile–ẹkọ giga (Ilesha Grammar School) ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti ti ni ibẹrẹ ọsẹ yi, ti nwọn si le gbogbo awọn ẹgbẹrin (400) awọn ọmọ Ile-ẹkọ na jade.

Ọgbẹni D. K. Olumofin, Minista Alamojuto eto ẹkọ fun Ipinlẹ Iwọ Orun sọ fun Oniwe irohin wa ni Ibadan ni ijẹta wipe, gbogbo awọn Ọba ati Ijoye pẹlu awọn enia sarakisaraki Ilesha ni nwọn ti wa ndọbalẹ ti nwọn si nbẹbẹ ni o jẹki awọn gba ẹbẹ, ti awọn si fi ṣi ile ẹkọ na pada.



Ọgbẹni Olumofin

Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni awọn ọmọ Ile–ẹkọ na ho le Oloye Akintọla ati awọn ẹmẹwa rẹ lori ni Ilesha.

Enia mẹtadinlogun ni awọn Ọlọpa ti mu, nwọn si wa ni itimọle awọn Ọlọpa bayi, bi nwọn ba ti ṣe ẹjọ na si ẹ ma a gbọ o.

# ẸJỌ OLOYE AWOLỌWỌ BẸRẸ LANA

EKO:- Gbogbo ile Ejo lo kunṣọṣọ ti ẹsẹ ko si gba ero fun ọkẹaimọye enia ti nwọn wa si Ile-ẹjọ gigajulọ fun Orilẹ–ede Naijiria nigbati Ile–ẹjọ na bẹrẹsi gbọ ẹjọ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ati awọn enia mẹrindinlogun miran pẹlu rẹ ti nwọn wa ni ọgba awọn nisisiyi.



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Ni deede agogo mẹsan kọja iṣẹju mẹdogun ni ile ẹjọ na bẹrẹ ijoko wọn lana pẹlu awọn adajọ marun lori aga ijoko idajọ.



Ọgbẹni B. Adedipẹ

Orukọ awọn adajọ na ni, Ọlọla Adetokunbọ Ademọla, Ọlọla Lius Mbanefo Olori gbogbo awọn adajọ Ipinlẹ Ila Orun Naijiria, Ọlọla John Idomora Conrad Taylor, Ọlọla Vale Bairamian, Ọlọla Lionel Brett.

Nigbati ọgbẹni Victor Durand, Agbẹjọro fun Oloye Awolọwọ bẹrẹ ẹjọ, bẹrẹsi ba Ile ẹjọ na sọrọ ni agogo mẹsan kọja ogun iṣẹju. O si pari ọrọ rẹ in agogo kan abọ ọsan.

Gbogbo Ile ẹjọ na lo pa lọlọ nigbati Ọgbẹni Durand mba Ile ẹjọ na sọrọ.

Ninu ọrọ rẹ, Ọgbẹni Durand sọ pe, "Oluwa mi, o jẹ ohun idunnu fun mi ti ẹnu ko le sọ lati le wa ni Ile ẹjọ gigajulọ orilẹ-ede Alailọba Naijiria, ti mo si ni anfani lati le ba nyin sọrọ.

"O yẹ, o si tọ ki nle dupẹ lọwọ nyin, Oluwa mi, mo si ro pe ọpẹ mi na yio jẹ itẹwọgba nitoripe eyi ni igba kini ti ngo kọkọ ba Ile ẹjọ kan sọrọ ni orilẹ ede yi."



Ọlọla Ade. Ademọla



Ọgbẹni Latifu Jakande

Ọgbẹni Durand tun ṣe alaye wipe on wa si Ile ẹjọ lati wa gbẹnuṣe fun Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ati awọn enia mẹtadinlogun miran pẹlu rẹ.

Awọn enia na ni: Michael Omishade, Gab. Shashore, Akinsanya, Onitiri, Obietoma, Jibowu, S. T. Oredein, Ekotiẹ—Yesin, Lateef Jakande, J. S. Ọlawọyin, Nwaobiala, Oyesile, Otubanjọ, Lawanson, Akamo, Umọrẹn, Akinsanya.



Ọgbẹni J. S. Ọlawọyin

Gbogbo enia lo ya ẹnu silẹ ti nwọn ko si le pade mọ nigbati Ọgbẹni Durand sọ wipe, "Oluwa mi, ti ẹ ba gba mi laye lati sọ, enikẹni ni o le ri i dajudaju pe ko si ohun kan ti a le ri dimu, tabi ti o le fihan pe, Oloye Awolọwọ gba ọna ẹburu ko awọn ohun ọsẹ wọlu lọna ti ko tọ."

Ọgbẹni Durand ni, "awọn abanirojọ pataki fun Ijọba ti kuna ninu iṣẹ wọn, lati fihan gbogbo enia gedegbe, ọna ti Oloye Awolọwọ gba ti o fi ko awọn ohun ọsẹ wọlu."

(Wo Oju Ewe Kẹfa)

# ỌRỌ OLOTU

## A ki Awọn Ọlọpa Ku Işẹ

Awọn Baba wa a ma a pa a ni owe wipe "Ẹniti a ba şe ni ore ti ko ba dupẹ, o dabi igbati Gambari ba ni loju ọna ti oko ẹru ẹni lọ" Awa oniwe Irohin Imọlẹ kesi Ọga Agba awọn Ọlọpa ninu iwe wa ọsẹ ti o kọja wipe, o yẹ ki nwọn mu ofin ti nwọn şe wipe ko gbọdọ si ipade ode gbangba iwọde kuro, ki awọn ara ilu o le ni anfani gẹgẹbi o ti wa ni akọsilẹ eto işelu wa.

Şugbọn o jẹ ohun idunnu fun wa wipe ni ọjọ karun ti Iwe Irohin Imọlẹ mu imọran na wa ni Ọga Agba awọn Ọlọpa gba imọran wa na, ti o si tẹle gẹgẹbi ati şe wi. Nwọn ni bi ọmọde ba dupẹ ore ana ari omiran gba. Iwe Mimọ Ọlọrun si sọ wipe, "Ọkan ti oba mọ ore, on ni ao mu sanran."

Adupẹ fun ofin ti Ọga Agba awọn Ọlọpa mu duro ni Ibadan ati agbegbe rẹ. Odi ọdun meji odin oşu kan loni ti awọn Ọlọpa tişe ofin wipe, ko gbọdọ si ipade ode gbangba ati iwọde ni Ibadan ati agbegbe rẹ şugbọn nwọn ti mu ofin na kuro nisisiyi awọn ara ilu si ni anfani lati şe ipade gegebi o ti şe wu wọn laiko di ẹnikeji lọwọ.

Şugbọn titi di bi ati şe nkọwẹ yi. ni awọn Ọlọpa si nlọ Ofin "işede" ni Eko, Mushin, Ikorodu, Ikẹja, Shomolu, Ẹpẹ, Badagry, ati agbegbe rẹ. Awọn enia na ko ni anfani lati şe ipade Ode gbangba ati iwọde ninu ilu wọn lati nkan bi Ọdun meji şẹhin.

Nisisiyi ti awọn Ọlọpa ti mu Ofin na kuro, ti gbogbo enia si ni anfani lati le maa şe ipade Ode gbangba gẹgẹbi o ti şe wu wọn, Awa Oniwe Irohin Imọlẹ sọ fun gbogbo awọn ti o nhuwa janduku ki nwọn lọ so agogo "gbejẹ e mọ ọwọ "ki nwọn si ye iwa janduku hu, nitoripe ẹru kan ni imu ni bu igba ẹru.

A si tun wa kesi awọn Ọlọpa pe, ki nwọn jọwọ, ki nwọn ma a mojuto gbogbo awọn "Alapamaşişẹ, ọlẹ-ku-ya" ti nwọn sọ ara wọn di ohun elo awọn ẹgbẹ Oşelu ati ma a huwa jagidijagan kakiri ilu. Ki nwọn jẹ ki ilu o ni alafia, ki nwọn o si ronu piwada ki asiko to kọja.

Awa rọ gbogbo awọn asiwaju ẹgbẹ Oşelu ti nwọn ma a ngbe mọto fun awọn "ẹhanna enia" lati ma a da rogbodiyan silẹ larin ilu pe, ki nwọn dẹkun iwa ibajẹ hu. Ko si ere kan ninu iwa ibajẹ bikoşe adanu

A si tun kesi awọn Ọlọpa pe ki nwọn ma a mojuto gbogbo awọn ẹhanna enia na gbogbo larin ilu ati igberiko, nitoripe, ẹniti oti sa tẹ osi ti tatanta, ko kọ ki ọja ma tu ni ọrọ iru awọn enia bẹ

Abẹ awọn Ọlọpa pe ti ọwọ ba tẹ awọn ẹhanna enia na, ki nwọn o ma şe aanu fun wọn nitoripe awọn na ki işe ẹni aanu O yẹ o si tọ ki ẹ lo ofin le wọn lori, eyiti yio jẹ arikọgbọn fun iru gbogbo awọn enia ti nwọn ba ni iru enia lati huwa bẹ

Awa oniwe Irohin Imọlẹ lero pe awọn ọlọpa yio se işẹ wọn, laibẹru, laişe gbe ati laişe ojusaju enia.

O yẹ osi to ki awọn ara ilu oni alafia ati ifaiyabalẹ larin ilu ki olukuluku enia osi ma a rin falala bi o ba ti şe wu u.

# Esan De Ba Orilẹ-ede Aiye

Gẹgẹbi mo ti mba Ọrọ iran ti mo ri bọ lati bi Oşu meji bọ lati ẹhin wa, ohun na ni ngo tun maa ba lọ ni Owurọ yi, eyi ni yio si jẹ opin awọn ohun ti Ọlọrun fi han mi eyi ti yio şelẹ nigbogbo aiye ninu Ọdun yi ati Ọdun ti mbọ.



**Woli Kogberegbe**

ọdun yi ẹ mura si adura nitori ifarapa ninu aisun ọdun o. Ọpọlọpọ ọmọ ni awọn enia yio jigbe l , ọpọlọpọ ija ni yio ma şẹlẹ ninu aisun yi o.

Ki gbogbo enia ko lọ şọra fun ija ni asiko yi o, nitoripe ọpọlọpọ oku ni yio ma sun nitori ija, Oluwa yio şẹgun alakoba o Amin.

Ẹ gba adura fun awọn agbẹ gidigidi nitoripe ọpọ ninu wọn ni ọwọ ọta yio ma tẹ lati inu oko wọn wa, ẹ mura nitori jamba ejo yio pọ ninu ẹrun ti a lẹ bọ si yi. ẹlomiran yio si ti ku si ile ti a ko si ni mọ wipe ejo lo bu Oluwa rẹ jẹ.

Ẹ mura si adura nitori eleyi, ọpọlọpọ ogun ti awọn ajẹ ti gbe dide pọ o, ẹlọ şọra lati ma fi jẹlu şe aşọ, ọta fẹ pọ ju ohun rere lọ, ẹ lọ şọra nipa ọrẹ ninu ọdun yi o Oluwa yio gbe gbogbo wa leke aiye yi o Amin o.

Ohun buburu kan yio jade lati inu ile wa si ode aiye nitoripe mo ri iho kan lori ilẹ, ko si fẹ ju ọmọ ri agolo lọ, iji lile kan si bẹrẹ si fẹ lati inu ilẹ na jade.

Ha! eyi ba mi lẹru ninu igbesi aiye ti mo wa yi, iji na si bẹrẹ si poyi bi şia Baba jade lati inu ilẹ na, eyi mu mi ronu wipe on buburu yio wọ inu aiye wa ninu ọdun 1964.

Ha! ẹ gbadura Ha! ẹ gbadura nitori pe ogun ẹkun yio sọkalẹ si ode aiye oloye kan yio fi aiye silẹ nilu Eko, okiki yio si kan.

Ẹ gbadura nitori ija nla igboro Eko, ẹ mura si adura nitori enia kan ti nwọn yio şapa si ilu Eko laipẹ yi.

Ifarapa yio pọ ninu aisun ọdun yi. ki olukaluku lọ kilọ fun ara ile rẹ nitori mo ri agbara ejẹ kan to bẹrẹ si şan lọ si Ile Iwosan (Hospital).

Mo si bere ninu iran mi wipe kini itumọ eleyi, nwọn si sọ fun mi wipe ki olukaluku ko şọra rẹ ninu aisun ọdun yi o,

Ẹ kilọ fun awọn Ọmọ nyin ko mọ lati jẹ sara, ẹlọ mura si adura nitori eyi o, ọkọ ofurufu kan yio şọnu ni ọna idalẹ ti nwọn ko si ni ri ọkọ na mọ rara eyi jẹ ohun ibanujẹ fun mi

Wahala yio de ba enia yio si de ba ẹranko igbẹ pẹlu nitori Ọlọrun fẹ gbẹsan lori ilẹ aiye. ẹ gbadura nitori-inu ininrin

Inu ọpọlọpọ enia ni yio ma gbona ẹ mura si adura

Wo Oju Ewe Karun

# Akinfosilẹ Fara Mọ Idaniduro Awọn Ọmọ Yoruba L'ẹnu Iṣẹ

Alaga ti ndari iṣẹ ẹgbẹ Alakukọ ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijira si sọ ninu ọrọ rẹ pe on fi ara mọ didaduro ti olori i l e iṣẹ ti Reluwe da ọgbẹni Modupẹ Alade duro gẹgẹ bi igbakeji ọga agba ninu ile i ṣ ẹ ti Reluwe, Oloye Akinfosilẹ si sọ ọrọ wọn yi ninu ọrọ rẹ nigbati ti o ba awọn onirohin nsọrọ n i ọjọ Aje ti iṣe ẹjọ kẹfa osu yi nip ọrọ ti ọgbẹni T. O. S. Benson sọ nipa didaduro ti wọn da ọgbẹni Alade duro.

Ọgbẹni Benson si kọ Iwe aitọ s i Olotu Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ti o si tun j ẹ olori ẹ g b ẹ Alakukọ Dokita M, I. Okpara, nipa didaduro ti wọn da ọgbẹni Alade duro ni ile iṣẹ t i Reluwe.

Oloye Akinfosilẹ si b u ẹnu atẹ lu iwe t i ọgbẹni T. O. S. Benson kọ si Dokita Okpara ati pe gẹgẹ bi nwọn ṣe da ọgbẹni Alade duro ko si faramọ iru nkan ti o nṣẹlẹ ni i p i n lẹ Iwọ Orun Naijiria nipa ihuwa si ti awọn ọ m ọ Yoruba nse fun ara wọn ti ko tọ ọna rara.

Oloye Akinfosilẹ s i tun sọ ninu ọrọ rẹ pe kinise ti awọn to si nse elegbeja fun awọn ọmọ Yoruba nisiyi ko jẹ ki awọn ọ m ọ Yoruba to jẹ osiṣẹ ni ile iṣẹ ti Reluwe ma gbọrọ si awọn to jẹ ọga fun wọn lẹnu ati lati le jẹ ki wọn ni itẹriba fun awọn to jẹ ọga fun wọn ninu ile i ṣ ẹ na. Oloye Akinfosilẹ si sọ pe inu on ko dun rara si awọn ọrọ ti Ọgbẹni Benson nsọ fun awọn ọmọ Alakukọ ti ilẹ Yoruba ti wọn si tun jẹ awọn ẹni to si ni igbẹkẹle ninu ẹgbẹ wọn N. C. N. C Oloye Akinfosilẹ si tun sọ pe Ogbẹni Benson ko si ni aṣẹ lati sọrọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ wọn to wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

---

## ✶ YẸ IRAWỌ RẸ WO ✶

AQUARIUS (Jan2i -Feb 19) Iwọ yio ṣe alabe pade alejo pataki kan lọiọ toni inu rẹ yio si dun de ọba.

PISCES (Feb 20–Mar 20) Ọrẹ airotẹlẹ kan yio de si ọ loni, ire ni yio si jẹ.

ARIES (Marh 21-April 20) Iwọ yio ṣe iṣẹ aṣẹjere kan loni ti yio si jẹ ire fun ọ lọpọlọpọ.

TAURUS (Apl 21-May 21) Ere faaji kan yio sọlẹ fun ọ loni tobẹ ti nkan yio mirigindin fun ọ.

GEMINI (May 22–June 21) Ọrọ nla pataki yio ṣẹlẹ, nitorina ki o mura, ki nwọn maṣe bori rẹ ninu ọrọ na.

CANCER (June 22 July 23) Bi o ti wu ki ori, owo diẹ yio tẹ ọ lọwọ loni, maṣe kọlati ba ẹnikẹni dije, iwọ yio bori

LEO (July 24 – Aug. 23) Ariyan-jiyan diẹ yio wa wa nipa ibikan ti o ngbero lati lọ lọwọ

VIRGO (Aug. 24 – Sept. 23) Ọkan ninu awọn iṣẹ ti o ma, yio ko ire airotẹlẹ wa ba ọ loni

LIBRA (Sept 24 – Oct. 23) Bi oba nfẹ ifọkanbalẹ ninu ile rẹ ohun to dara ki o ṣe ni wipe, ki o gbọrọ si awọn ọrẹ rẹ lẹnu

SCORPIO (Oct 24- Nov. 22) Maṣe na inakuna loni ki apo rẹ ma gbẹ ki ilẹ to ṣu

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 22) Bi o tilẹ jepe ọjọ oni le diẹ maṣe foya, ayọ mbọwa lẹhin rẹ. Ọrọ sisọ yio pọ nibẹ

CAPRICORN (Dec. 23 – Jan. 20) Mura silẹ nitori ayipada re yio de si ọ titi ọjọ alẹ

---


# Iboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara

Awọn Egbogi Rọbirọbi ti wọn nta kakiri Igbor joko le ṣe Iwosan wọn lailai afi ki o ri ojulowo Egboo ilu ko ti o ba lagbara gidigidi lati le hu Ikọ na lati ibgi "Ikọ" si ti o si ti gbilẹ Fun awọn iru Ikọ bẹ yẹ iti oti bere fun egbogi wọnyi:

## "Thmo-Ephedrin" Tabi Egbogi 'Linituss'

Fun iwosan ikọ Asima, ikọ fere ikọ otutu igba-aiya ikọ Igbẹdu, ikọ-ọnafun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ọna-ọfun tabi pẹlu kẹlẹbẹ tabi ti o ma njẹ ki enia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsan ati oru-gbiyanju lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara gidigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugburu larin wọn si awọn olomi ṣorokiti ti wọn nta kakiri. O daju nbẹ iwọ yio bẹrẹ si ri alafia, iwọ yio ma jẹun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yẹn Bere ni Ṣọbu awọn:—

Bere egbogi ajẹbina Richelet y ni ṣọbu awọn

Waterloo Medicine Store
8. Plamchurch Street, Lagos
Phone:–2287 Nigeria, (Ojuɡ ita F. ji)

(2) Adedun Chemist
4 Wakeman Street, Yaba


---

# E ma ka Irohin Imọlẹ Lojojumọ

---

# Igbimọ Atunto Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

GẸGẸBI ati fi aṣẹ fun mi lati ọdọ awọn Igbimọ atuneto ẹgbẹ Imọlẹ Aiye pe, nwọn ti tu ẹgb Imọlẹ Aiye tẹlẹ ka, a si ti tun da omiran silẹ n torina ti o ba ri pe o fẹ jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ tẹ tun yi ki o kọwe si mi ki o si ri pe o wa si Ipade ni ọjọ kọkanla oṣu kẹrin (11/4/64) ni dede agogo mẹta ọsan.

Ẹgbẹ yi yatọ si ti atẹhinwa a si tun ti ni ofin titun miran, Eyi si ni awọn ere ti ẹgbẹ titun na yio ma

1. Lati maa kọ awọn ọdọ ilẹ yi ni ọna bi a ti nkọ irohin, itan, ọrọ sinu iwe Irohin la i ọdọ awọn Ọjọgbọn oniwe Irohin
2. Ere bi Bọọlu alafẹsẹ gba, Table Tennis, Swimming, Entertainment, Ayo Iṣẹ. Draft Ludo Picnic ati ọpọlọpọ awọn nkan miran ti eo ma a gbọ ni ipade.

Nitorina ti o ba fẹ tun jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ, titun yi ki o wa si ipade ni ọjọ 11/4/64 ni nọmba 16 Bamgbọṣe St., Lagos, Ao si tun yan awọn alaṣẹ ẹgbẹ titun.

Eyi ni orukọ awọn Igbimọ atunto ẹgbẹ Imọlẹ:—
J. Ọla. Okunlọla
Latifu Babalọla
Sedu Olupo
Abudulai Awẹlẹnjẹ
Timothy Akins
Ẹ jọwọ ẹ tete de ipade o.

# Abayori Orire Ti Ijoba Ipinlẹ Iwọ—Orun

Gẹgẹ bi ikede Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun, agbọ wipe ẹniti ọra tikiti orire J003002 ni ogba ipo kini ti yio si gba ẹdẹgbaji ponun (£3000) nibi idije karundinlọgọta ti wọn se ni gbọgan Mapo ni ọjọ ọjọ Bọ ti se ọjọ keje oşu yi.

Ẹniti ogba ipo keji ni ẹniti ora tikiti B004202 yio gba ẹgbẹrun pọnun (£1000

Ẹniti ogba ipo kẹta ni ẹniti ora tikiti F006981 yio gba ẹgbẹta pọnun (500).

Awọn marun mirsa ti nwọn tun se orire ti nwọn yio si gba owo ọgọrun pọnun (£100) ni awọn ti nwọn ra tikiti nwọnyi J003032, B008314 L003864, B008690, H006915

Adọta enia ni nwọn ti se orire ti nwọn yio si gba owo pọnun mẹwa mẹwa, Awọn ni nwọn ra tikiti nwọn yi:-

K002106, K002260, C003868,
B005843, N009564 A000967,
N006192, C009898, M004996,
M005823, E002948, F007575,
C001215 F005560, A005690,
I002741, F008046, A005080,
B002040,
A001029, D006565, H006536,
H002076, H003201, E002553,
M005616, F008138, L006095,
G003883, I007611, B009991,
E006964, G007846, A002572,
F009566, C007173, A002098
D006789, H006154, B006761,
A005649, J005792, C008600,
A003741, C003000, A003814,
J000720, F005804, C006263,

Ọgọrun enia ni o tun se orire ti nwọn yio si tun gba owo pọnun marun marun (£5) awọn ni nwọn ra tikiti nwọn yi:-

B008885, G005447: F001740,
C006501, E001238, J004547,
B008311, B002180, F005856
J004855, C005674, B000205,
J000588, C008226, D006712,
B005993, I004620, F003498,
C005496, C008984, H002930,
C000056, E001888, G003670

D001501 GOO7816 F005100,
F 001565, M 009467 C 000530,
B0003292, B 001887, L 003652,
I 002601, J 003608, A 007132,
N 005040, I 001462, A 004813,
C 004997, D 001330, E 005195,
L 005194, F 009352, H 000045,
F 001983, A 005823, E 007699,
F 009425, E 004493, A 009756,
A 004225, B 000737, B 005377,
J 003917, N 008836, B 008513,
E 000542, D 009202, B 000124,
I003336, G001247, F008246,
F007256, G004476, B003797,
M009030, E008842, N006916,
F009984, E007720, E006586,
B005803, E005780, B009692,

B004512, L005406, J001121
B005214 D008016, M002391
B001712, A005660, D003637,
A009325, K005116, G008431,
F000583, E003940, L000568
D002635, H003510, A005427
D001123, A001366, D004548,
B008169, G000754, ati
A001103.




## LATI OJU EWE KEJI

nitori eyi o. Ọga awọn Ọlọpa kan yio ku Obinrin ni yio pa eleyi. Ẹlọ mura si adura nitori eleyi o.

Ọkọ oju omi kan yio so jamba, lati Eko si ilu Ẹpẹ ẹ mura si adura nitori ẹmi enia yio sọnu pupọ ninu ọkọ oju omi na o.

Igba meji ni ọkọ oju omi yi yio danu, ọkan yio danu ni alẹ patapata, ọkan yibo danu ni agogo mẹfa arọ.

Ẹ lọ mura si adura, ni yio şezun ibi wọn yi. Ha! iku mọto kan yio şẹlẹ ni ọna Ghana, eyi ba mi lẹru pupọ nigbati ọmọ enia yio ma ku bi ewe bọ lara igi.

( digba kan na

## Kere o

10TH BOOK OF MOSES: Iwe kẹwa Mose, Iranlọwọ nla fun awọn Ẹgbẹ Aladura lọna iwosan, ifihan, asọtẹlẹ. Aşiri imularada lọna orişirişi, aşiri isọ agan di ọlọmọ, igba ni lọwọ awọ awọn agbaalagba. Agbojọ, ki a wi bẹ ẹ ki o si ri bẹẹ lọnakan, mayehun atata. Pọnun kan (£1) pere. A le ri i ra lọ dọ MANAGER 15, Araoti Street, Yaba-Nigeria ati ni ọdọ awọn wọnyi: Abudu Akangbe, Ile Tabintie, Ikire via Ibadan, David Taiwo, 19, Ajegunle Street, Ilupeju, Mushin ati Thomas Akinkunmi, c/o- Dr Ayọ Alade, Oke Elerin, Ogbomọsho.

## Kere o!

Fun anifani gbogbo enyin onişowo, Iwe Irohin Imọlẹ yio şe ipolowo awọn ọja nyin fun nyin ni ọsẹ kan gbako ki ọdun Ileya o to de ati lẹhin ọdun ki awọn onibara nyin le ba nyin ra ọja ti ọdun Ileya ti mbọ yi.

Awọn Aşoju wa yio ma a lọ kakiri lati bere fun awọn ti o ba fẹ lati polowo ọja wọn ninu fIwe Irohin wa.

Owo pọọku ni a ngba, dan wa wo lẹkan ki o sri bi ajo rẹ yio ti ta to,Ijafara lewu o.

## EGBOGI JẸDIJEDI

FUN EGBOGI



## "CYCLOVE"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara idi si nyọ ọ lenu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho rẹ enia ibiti a ma ngbe şe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amod ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati şe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma po- owo wọn fun iwosan rẹ şugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le şe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Şugbọn awa ko ro be rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun berẹ bakana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o berẹ nipa aiko ma şe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna şelu lojojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Şuga tabi oniruru ohun adidun pupoju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ jade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba şe igbọnşẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "GYCLOVE" ti awọn Oyinbo Jamani şeşẹ wa idi rẹ a ki o si danwo orişi meta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi na pata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogid taa- a gboro ilu Naijiria jakejade. Bere rẹ ni:—

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 577 SATURDAY, APRIL 11, 1964 (2D)

## Nwọn Ji Aye Oni Gbe

Ibadan:- Gbogbo ero ti nwọn pejọ si ile ẹjọ kekere kan nilu Ibadan ni nwọn ku sẹrin bi awọn ọlọpa ti nsọ fun ile ẹjọ wpe awọn ọdọmọkonrin meji kan, Karimu Amao ati Ẹmiọla Alao ji Aye oni gbe.

Awọn ọlọpa sọ pe ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu kẹta ọdun yi ni awọn ọdaran yi wọ agbala ile Ọgbẹni James Tegunde ni adugbo Isalẹ Afa ti nwọn si fi ọgbọn gbe aye ọni na lọ.

Nwọn sọ pe owo ọni na jẹ pọnun mẹdogun (£15). Awọn ọdaran mejeji ti sọ wipe awọn ko jẹbi ẹsun ole jija, ti awọn ọlọpa fi sun awọn. Adajọ si ti sun gbigbọ ẹjọ na si ọjọkejidinlogun oṣu kẹrin ọdun yi.

Bi nwọn ba ti ṣe ẹjọ na si, ẹo ma a gbọ.

# AWỌN ONIṢOWO PE IGBIMO MUSHIN LẸJỌ

IKẸJA:— Gbogbo ọgba ti o yi kotu giga Ikẹja lo kun ṣọṣọ ti ẹsẹ ko gba ero lati woran ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹjọ oṣu yi nigbati Adajọ Agba Ọlọla J. A. Kester ngbo ẹjọ ti awọn oniṣowo ọja Mushin nba Ijọba Igbimọ Ibilẹ Mushin ṣe lori Isọ itaja wọn ti Igbimọ Ibilẹ na wolulẹ lẹnu lọlọyi.

Awọn obinrin oniṣowo ti o pe ẹjọ na ni Iyalode Abadatu, Sibiyatu Asabi, ati Badaru Lafẹnwa ti nwọn ṣe Aṣoju fun gbogbo oniṣowo ọja Ararọmi Mushin.

Awọn oniṣowo na pe akowe Ijọba Igbimọ Ibilẹ na Ọgbẹni L. O. Ọmọtọsho ati awọn oṣiṣẹ wọn lẹjọ ti nwọn si tun fẹ gba owo itanran ẹgbẹta pọnun (£500) fun Isọ wọn ti nwọn baje.

Ninu ẹjọ won' awọn oniṣowo na rọ Adajọ wipe ki o fi ofin de awọn Ijọba Ibilẹ na ki nwọn maṣe di awọn lọwọ fun ati le ta ọja ni Isọ awọn na.

Ninu ẹjọ tirẹ, Ọgbẹni Ọmọtọshọ ti iṣe akowe Ijọba Ibilẹ Mushin fi han ile ẹjọ giga na riran ti on ran awọn oṣiṣẹ lati lọ tu ọja Mushin ka jẹ aṣẹ lati ẹnu Igbimọ ti nmojuto ilu (Mushin District Council.)

O tun tun sọ wipe Igbimọ na ti ya owo (£67.090) lati le fi kọ ọja titun ti awọn si gbọdọ san pada.

O ni larin ọdun kan owo ti awọn gbọdọ san fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti o ya awọn ni owo yi jẹ Ẹdẹgbẹrin pọnun (7,000) Ọgbẹni Ọmọtọshọ ni iṣoro nla ni o jẹ fun Igbimọ Ibilẹ on lati le ko owo Ẹgbaa pọnun (£2,000) jọ larin ọdun kan nitoripe ko si enia nibẹ.

Iya afin Abadatu tiṣe Iyalode fi han ile ẹjọ wipe, o ti to ọdun mẹdọgbọn ti awọn ti nta ọja ninu isọ Ararọmi yi lai si Ijangbọn.

Oni awọn ti lọ fi ọrọ na han Igbimọ ibilẹ ṣaju ti Igbimọ na si gba lati ṣe amojuto ki nwọn to ran awọn oṣiṣẹ wọn wa lati le awọn ni ọjọ keje oṣu kẹta ọdun yi lai ro tẹlẹ.

Oni igbati awọn ngbọ hunnu-hunnu labẹlẹ nipa ọrọ ọja yi ni awọn ba ri ẹniti nṣe Alaga Ijọba Ibilẹ na ọgbẹni Adeniran Ogunsanya ti o si ṣe ileri wipe on yio ṣe ayẹwo ọrọ na. Ki ile ẹjọ na to tuka ni ọjọ yi ni Adajọ Agba na Ọlọla J. A. Kester lọ yẹ ọja Ararọmi na wo

O si ti sun gbigbọ ẹjọ na di ọjọ kẹjọ oṣu karun ọdun yi

## Ẹjọ Awọlọwọ Bẹrẹ Lana

(Lati Oju Ewe kini)

O tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ ti gbogbo enia lo gbọ pe, Dokita Akinwumi Maja fi ẹnu ararẹ sọ wipe o ngbero lati fọ Ile Igbimọ Asofin Apapọ Ijọba Naijira nigbati awọn ọmọ Ile Igbimọ na ba nṣe Ipade wọn lọwọ.

O ni, Dokita Maja tun sọ wipe, on ra awọn ohun ọṣẹ kan lo si Abẹokuta lati ma a fi fọ okuta, o ni ẹdẹgbẹta pọnun (£500) ni Dokita Maja sọ wipe on ra awọn onun ọṣẹ kọọkan.

Ọgbẹni Durand tun sọ wipe "O jẹ ohun iyalẹnu wipe, nigbati adajọ nṣe idajọ, ko tilẹ mu ẹnu kan ọrọ Dokita Maja ti o sọ pe, on yio fi ohun-ọṣẹ fọ Ile-Igbimọ Asofin Apapọ Ijọba Naijiria ati awọn Ile patakipataki ni arin igboro ilu Eko"

O tun ṣe alaye pe, ki iṣe otitọ pe, awọn enia na fẹ gba Ile iṣẹ awọn ọmọ Ogun Naijiria ati awọn ọmọ Ogun ọkọ oju omi pẹlu ina Lẹntriki, pe nigbati nwọn ba pa ina Oloye Awolọwọ yio wa lọ sọ lori ẹrọ Redio pe, on ti di Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria.

Ọgbẹni Durand wa rọ Ile ẹjọ pe, ki nwọn o maṣe kọ ibi ara si arosọ ọrọ na, nitoripe ko ni ẹsẹ nilẹ.

Gbogbo Ile-ẹjọ lo bu si ẹrin nigbati Ọgbẹni Durand sọ pe "Bi o ba jẹ wipe Oloye Awolọwọ ba di Alakoso Ijọba Orilẹ-ede Naijiria, ki iṣẹ ti Naijiria nikan ni yio jẹ mọ, ṣugbọn ti gbogbo aiye titi de ilu Ọba Gẹẹsi ni yio jẹ pẹlu"

O wa rọ ile ẹjọ pe, bi on ba ṣiṣẹ ninu iṣẹ on yi, inu on yio dun bi nwọn ba lepe akiyesi on si aṣiṣe na.

### IṢẸ AJE

Ọgbẹni Durand tun ṣe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ pe, ninu ipade ti awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe, (eyi ni Igbimọ ọgbọn ori-ati Alabẹṣekele) nwọn pinnu wipe, ti ẹgbẹ Afẹnifẹre ba le bori ninu ibo apapọ nigbana, Ijọba awọn ko ni ba enikẹni ṣe ọta ninu awọn Oyinbo alagbara aiye, eyi ni yio si fun awọn enia na ni aye lati le ma a wa da iṣẹ owo ati iṣẹ aje silẹ ni Naijiria ki o ma si ṣe si airi iṣẹ ṣe ati alta ọja larin ilu.

O tun ṣe alaye pe, ọjọgbọn enia ni Oloye Awolọwọ, ko si si eniti o ri iwa tabi ẹniti o gburo iwa aidara si ri ni ọjọ kan, titi di igbati ẹjọ rẹ yi bẹrẹ.

O ni ẹnikẹni ni o si le gba pẹlu on ninu ọrọ na pe, otitọ ọrọ ni on sọ.

O wa ṣe alaye pe ẹri ti Dokita Ọnabamiro jẹ niwaju adajọ ki iṣe ẹri otitọ, on si nbọ wa tu aṣọ loju eegun eyiti yio mu gbogbo enia gba pẹlu on pe, "Ọnaba iro ki iṣe olotitọ enia"

Agbejọro na bẹrẹ ọrọ rẹ ni deede agogo mẹsan kọja ogun iṣẹju o si pari ọrọ rẹ ni agogo kan abọ ọsan.

Oniwe Irohin wa Ejongboro fi ye wa pe, Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ko wa s Ile-ẹjọ na lana, enia mẹtala lo wa si Ile-ẹjọ ninu awọn Olujẹjọ na

Ile-ẹjọ na ti pari ijoko wọn o si tun di ọtunla ọjọ Aje ti tiṣẹ ọjọ kẹtala oṣu yi ki nwọn to tun bẹrẹsi gbọ ẹjọ na,

O darọ o.

AKARA TU S'EPO!

Iwe Itumọ Ala na ti de!!

Eyi ni lati kede fun awọn onkawe Irohin Imọlẹ pe Iwe Itumọ Ala lati ọwọ Joseph Alala ti jade fun tita nisisiyi. Iwe Ala yi yatọ si Iwe ala miran nitoripe Odu Ifa ni nwọn fi tumọ rẹ Egbogi jaburata si wa ninu rẹ pẹlu. Tete ra tirẹ ki o to tan.

Iye Owo:— Iwe kan 5/-
Dọsini 36/-
J. O. SHOYINKA
N2/99 Shittu Street
Ibadan

Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street P O Box 1495 Phone Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M. S. Grammar School) Bariga Lagos (11/4/64) 21985